# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VOL XIV NO 942 LAGOS SATURDAY OCTOBER 10—OCTOBER 16 1964 KỌBỌ MEJI (2D)


# Awon Danadana Eko Jawo Gba Ni Gbangba Ode Ni Abeokuta

ABẸORUTA — Awọn akọwe ile iṣẹ awọn oni siga (Nigerian Tabacco Cempany) ti nwọn ngba owo kiri lọwọ awọn onibara wọn pade agbako awọn danadana kan ni Ibara ni ọsan ijẹta, nwọn si ja ẹgbẹdogun pọnun (£3,000) gba lọwọ wọn.

A gbọ wipe mọto ayọkẹlẹ kan ni nwọn gbe wa si ile iṣẹ awọn onisiga na ni ọsan-gangan ti nwọn si bẹrẹsi yinbọn lati le awọn aladugbo kuro ni itosi.

Nwọn ni gbara ti ọwọ wọn ti tẹ owo na tan oju ferese ni nwọn gba jade, ti nwọn si bẹ sinu mọto ayọkẹle wọn, ti nwọn sare gba ọna Owode mọ Shagamu titi ti nwọn fi poora ni ọna Shomolu leti Ikẹja nigbati nwọn foju kan awọn Ọlọpa kan ti awọn Ọlọpa Abeokuta ti tẹ waya si wipe ki nwọn ba awọn mu wọn.

Awọn Ọlọpa ko ti ri wọn mu, nwọn si wa lẹnu nwọn nwa awọn danadana na kiri lọwọ.

## Olopa To Mu Enia Daran Owo

JOS — Ọga Ọlọpa didandoka kan ti orukọ rẹ njẹ S. Dikku ti o ṣiṣẹ fun Ijọba ibile Gombe ni a gbọ wipe adajọ-agba kotu awọn ọlọpa kan, Ọgbẹni J.R. Jones ni ki o lọ san pọnun kan o le ni adọrin pọnun fun gbigbaleti ti o gba ọkunrin Hausa ti o njẹ Sule Maimagani lọjọ ti o mu u ni ilu Gombe.

Gẹgẹbi ẹjọ ti Sule Maimagani pe ọga ọlọpa na si kotu, o ni lọjọ ti ọlọpa na mu on nṣe ni o fa agbada on ya ti o si ko igbati bo on, lẹhin eyi o tun ti on mọle ni ainidi.

Lọya kan ti o ṣe agbẹjọro fun Sule nị ofin ko sọ wipe ki Ọga Ọlọpa yi gba ẹnikẹni ti o ba mu leti rara, kini o tun wa fa a ti o fi ya Sule ni agbada; O ni orisirisi iwa buruku ti awọn Ọlọpa nhu s'ena ni ilẹ wa ni adajọ na ngbọ yi.

Ọga Olọpa na paapa ja fitafita nitoripe agbẹjọro Ijọba Ipinlẹ Ariwa kan ni nwọn mu wa lati Kaduna wa ṣe atako ẹjọ na lati sọ wipe iwa ti Ọlọpa na hu si Sule kotọna ṣugbọn adajọ ti o gbọ ẹjọ na ko gbagbẹrẹ rara. O ni ọrọ wọn ko ta rara lọdọ on.

## Ejo Ogun Doherty Di Atunro Ni Kotu Ganran

EKO — Ni ọjọ Aje ti o kọja yi, ni ijarun ni adajọ kotu ganran; Oloye G.B.A. Coker pa laṣẹ wipe ki nwọn tun iwe ẹjọ kotẹmilọrun ti Oloye Theophilus Adebayọ Doherty gbe wa si kotu nipa ọrọ ogun dukia baba rẹ, Ologbe J.H. Doherty ti ọkan ninu awọn ọmọ rẹ, Adajọ Richard A Doherty fi igba kan pe wipe on fẹ ki nwọn yọ ọwọ rẹ kuro ninu iwe babasinku patapata.

Ninu oṣu May ni ọdun yi ni adajọ agba kan ni ki nwọn fa iwe ẹjọ kotẹmilọrun na ya nigbati nwọn gbe e wa si iwaju rẹ ; o ni Ọlọla Adebayọ Doherty ko tẹle ilana ẹjọ ti nwọn kọko da, nitorina ko to lati tun wa pe ẹjọ kotẹ-on-lọrun rara.

Ninu ọrọ alaye ti adajọ Oloye Coker sọ ki o to paṣẹ wipe ki nwọn tun fi iwe ẹjọ kotẹmilọrun na si kotu, o ni Ọgbẹni Richard Doherty ti o pẹjọ naa ko sọ wipe iwe ẹjọ kotẹmilọrun yi le ko ba ẹjọ ti nwọn kọkọ da awọn. O ni on ko si ri iwe ẹlẹjọ na gba wipe on ko faramọ ki nwọn tun mu iwe ẹjọ na wa si kotu lati gbọ ọkan ti Oloye Bayọ Doherty yio ro.

Ni ọtunla ọjọ Aje ni nwọn yio ro ẹjọ na niwaju adajọ agba kan ti orukọ rẹ njẹ (Alekisandi (Alexander) ni Ọdan l'Eko,

# Oyinbo Panapana Ji Iwe Eri Moto

EKO — Ọgbẹni Bernard Lewis Henry Lefley, eni ọdun mẹtadi adota ti nṣe ọga agba awọn panapana ni igboro Eko, a gbọ wipe awọn ọlọpa ti mu fun ẹsun yiyi iwe ṣiṣe ẹda iwe ati jiji iwe eri moto kan ti apapọ iye owo rẹ jẹ pọnun mejila, ṣ e meje (£12:7: ) eyiti o je ti ijọba o si sọ pe on ko jẹbi awọn ẹsun wọnyi niwaju adajọ.

Gẹgẹbi alaye ti awọn ọlọpa ṣe nwọn ni ọgbẹni Lefley ti o jẹ Oyinbo alawọ funfun to si ngba oj diẹ egbẹsan pọnun (£1,860) lọdun ni o mu iwe eri moto ti ba ti nọmba rẹ je LG 348 o si fi si iwaju moto tirẹ ti nọmba rẹ je LG 9355.

Ṣiwaju agbejọro ijọba Ọgbẹni Ibidarọ Obe ti kokọ tọrọ gafara lọwọ adajọ lati ṣe atunṣe kekere kan ninu ẹsun keji lori iwe ẹjọ na Nina ṣe ki nwọn ni Oyinbo yi ji iwe eri moto kan laarin oṣu kẹrin ati ikẹjọ ọdun 1964, ṣugbọn Ọgbẹni Obe ni ko jẹ pe laarin awọn oṣu keji ati ọjọ kẹta oṣu kejọ ọdun 1964 Nina ẹsun keji nwọn ni o ti bo ni ṣe idakọ iwe eri moto ti nọmba rẹ je 193/027005 laarin oṣu kẹrin ati ikẹjọ ọdun 1964, ṣugbọn ki o jẹ pe laarin awọn oṣu keji ati ikẹjọ ọdun 1964.

Ọgbẹni Joseph Adeyemi Cole, to jẹ ọga agba lọọya miran ọgẹ J. G. Bentle ti nwọn ngbejọro fun ọgbẹni Lefley ṣọ pe ẹsun ti o mu ... ṣe ko fi ẹ ti oyinbo ra iwe eri moto na fun ...

Ki o to di pe nwọn fi ... dagun oṣu ... adajọ ... nwọn m... oyinbo ... ọgbẹni Abdue Raheem Bakare ... loya oyinbo ... wipe ọdaran na ...

ilu sile ni kete to ba fi iṣẹ sile gẹgẹbi nwọn ti sọ siwaju ọgbẹni Bentley si ṣe ileri na fun adajọ.

# Awon Olopa Meji Wewon Ni Ilu Nairobi

NAIROBI — Ni ọjọ kini oṣu yi, a gbọ wipe awọn ọlọpa meji ni nwọn sọ sewọn ... ẹsun fifi ... je awọn eni meji ti nwọn wa ni itimọle ... ọgba awọn ọlọpa ni ilu Nairobi.

Okan ninu awọn ọlọpa na ti orukọ rẹ nje James Kenyatu je lọ sẹwọn ọdun mẹta pelu bilala mejila enikeji rẹ to nje Godfrey Mwangi Kabanga si lọ sẹwọn ọdun mẹrin pelu bilala mejọ, awọn enia meji miran ti nwọn tun wa ni atimọle ... nkan yi ṣe e awọn Ọgbẹni Peter Njuguna Ncroge ati Maina ... jẹbi awọn mejeji si lọ sẹwọn ọdun mẹrin pelu bilala mejọ.

Ọgbẹni ti fisun fun ijọba Ọgbẹni S. Hawkins ṣe alaye fun adajọ pe pasan tabi kumọ ni awọn ọlọpa meji si fi lu awọn ara ilu Arab ati Asia ti ... wọn ti ... ọgba awọn ... won lele ọjọ ni ọgba awọn ọlọpa o si tun sọ pe iru ... yi jẹ eyiti o buru pupọ.

# Adajo Ni Oju Ti Fun Odaran Kan

YABA — "O ... ti mo ... Abeokuta ni o ... wa." ... awọn ọlọpa ... kotu kekere to wa ni Yaba so fun ọdaran kan ti orukọ rẹ nje Abu Bakare to ... Mu ... to si ... gba ... mẹrinla ninu

ọgba ẹwọn nigbati awọn ọlọpa mu wa siwaju rẹ nitoripe o ti igo ọti kan ni Oyinbo ni ọjọ kẹfa oṣu yi.

Alaye ti ọlọpa ṣe ni wipe Abu lọ si ibi kan ti nwọn nta ọti lati ra ọti kan ṣugbọn ko ... wọ ọti to ra ki o to yọ lọ nigba ti owo ... ọdaran na o ṣe pe o ... ko mu ... kankan ṣugbọn nigba ... nwọn yẹ ... ẹwọ ... wọn ba igo ọti lara rẹ.

Nigbati o mọ pe on jẹbi o ti bẹ adajọ pe ki o ṣanu on bi o ti jẹ pe ọmọ Abẹokuta ni o ... je n bini ... won gbe ... bi adajọ F. A. S. Ogunmuyiwa ati latimu ki o ... di adajọ loju o ṣeilee pe on ko ni mu ti mọ bi o ti jẹ pe o ... ni o nfa iṣubu fun on nigbagbogbo ninu adajọ ti ọgbẹni Ogunmuyiwa ṣe o ni oju ti on fun Abu ti ko ri ohun kan ka bikoṣe igo ọti kan ati wipe ninu awọn akọsilẹ ti Abu ti ni tẹlẹ o daniloju pe eni ibi ni o jẹ o ba sọ sẹwọn lọdun meji pelu iṣẹ aṣekara ki o si wa ni abẹ abojuto awọn ọlọpa fun ọdun mẹta gbako lẹ ... o ba ṣẹwọn tan.

# Olotu Pade Ola

(O bere ninu iwe wa ọsẹ to kọja)

Olotu – Nigbana nkọ ?
Ọla – Nigbana nbẹ
Olotu – O wa ... mi ni arifin ... gbe mọ ile pọọ.
Ọla Arifin kankan ko rẹ e isọrọ ni igbesi, isun'musi ni gbe'e soke.
Olotu – Tani kọ iwọ ari ke yi ni owe iwọ ade Eko di ere.
Ọla Mo gba ara oke kiṣe eebu ... ẹ ba ... ya ... pẹtẹsi kẹ mọ gun ki ẹ sọ wipe enyin ki ṣe ara oke
Olotu – Ọgbọn tirẹ mọ ti bọ ... di
Ọla – Bẹni Ọ ọrun jẹki won tete ṣe ofin iwe irohin gbogbo owo nyin ni nfẹ gba tan mo ri e ti ba mi lorukọ jẹ
Ọla – Ko bu u, ki obinrin tọ atọrin ki ọkunrin tọ atọrin ki a wo eni ... aso rẹ yio ... in
Olotu – Alufa to ni iyan yio mu ko mọ ni yọ on na sile
Ọla Tani mọ okolo lọyọ
Olotu – Ni ọjọ ti o kun'e nkọ ?
Ọla – Alafia ni o wa,
Olotu – A ... o ... ire ko pe ?
Ọla – Eyi ti o ku na ni mo wa de ọdọ nyin

(koiti pari)

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI–OFE ti o kun fun irohin aladun losose.

# Igbimo Oluwadi Lori Ofin Titun

EKO — Ọgbẹni Frank Oputa Otutu to jẹ olugbimọ nile igbimọ nla l'Eko tį da laba nipa ṣ ṣe ofin lorį dida įgbįmọ Oluwadį silẹ ti y o jẹ ajọ esia mẹrin pere lor atunṣe ofįn titun nipa titẹ iwe įrohin ti ọdun 1964, eyiti nwọn yio mẹnu kan ninu ipade ile igbimọ nla ni Eko ni Owurọ Ọjọ Abamẹta to kọja.

Ki o to dį wipe įle igbimọ kekere ti įsalẹ tuka nį alẹ Ọjọ Aje to kọja nwọn ti fọwọ si ofįn titun na. Gẹgẹbi Ofin ile igbimọ aṣofin ijọba nwọn nį aba ti Ọgbẹni Oputa Otutu da ko tį le ni akọsilẹ gẹgẹbi atunṣe lori ofin tįtun na lakoko yi, afi bi o ba jẹ wįpe o ti ṣe asọtẹlẹ bi ọjọ ma un șįwaju nitoripe bi o ba jẹ larin įpade igbimọ yi nį ọrọ yį jade, Olugbimọ na le mẹnu kan ọrọ yi jade Olugbimọ na le mẹnu kan ọrọ n a.

Atunṣe ti Ọgbẹni Oputa Otutu da laba ni pe ko si Oludasilẹ agbewe irohin jade Akọwe irohin tabi ẹnikẹni to ba lọwọ si titẹ rohin kan jade ti ijọba le ba ṣẹjọ fun titẹ ọrọ abuku tabi eyitį o mu ẹbi danį labẹ itọsẹ ofin kẹrin lori titẹ iwe įrohin laijẹ aṣẹ to tįle igbimọ Oluwadi jade wa na.

Nwọn ni anfanį wa fun ẹnikẹni ti įjọba ba mu lorį ofin titun yi latį gbọ ẹsun rẹ tẹlẹ ati lati ṣe alaye fun ara rẹ siwaju igbimọ Oluwadi na.

Awọn ti yio jẹ ọmọ ẹgbẹ yi ni awọn bį aṣoju kan lati ọdọ ẹgbẹ awọn oludasẹ iwe irohįn silẹ, aṣoju ile iṣẹ eto ofin kan ati aṣoju kan ti o ma wa fun awọn ara ilu, on papa si nilatį jẹ loya to ti ușiṣẹ latį bi ọdun mẹwa sẹhįn. Ọrọ na fai pupọ ki o to dį pe įle įgbimọ tuka.

## e ka oro osise

(loju ewe kẹfa)

# Nwon Da Adajo Kan Duro Ni Ibadan

IBADAN — Oloye G.L Adeoiran tį nṣe adajọ agba kootu įbilẹ kan ni Ibadan ni a gbọ pe awọn ti da duro lẹnu iṣẹ lọsẹ to kọja,

Idaduro yi ni o tẹle iwe ẹbẹ kan ti alaga igbimọ aṣofin idabobo fun ẹgbe Alakukọ ni Ibadan kọkọ kọ siwaju si igbimọ ijọba ibilẹ ti Iwọ - Ọrun; ninu eyitį o ṣe aroye lorį iwa

(Wo yoku loju ewe kẹfa)

# Baba Aladie



Aworan oke yi ni ti Ọkunrin kan ti o nkọ iṣe Adiẹ titẹju ninu Ọgba ikọsẹ Ọhun ọsin,

# ELETI – OFE

(A NJU WON KO SE WI LEJO)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI QFE" Lagos
P. O. Box 467, Phone 23370

VOL. XIV. NO 942 SATURDAY Oct. 10 – Oct. 16 1964

## ORO OLOTU:

# Ise Oluko Kanpa!

Boya nigbati ẹnyin ọkawe wa ba n'a iwe Eleti-Ọfe ti ọsẹ yi awọn minista alamo,uto eto ẹ·ọ awọn ọmọ wa yio ti pari ọrọ awọn olu·ọ ti nwọn da iṣẹ silẹ patapata kakiri ilẹ Nigeria. ṣugbọn eyi ko sọ wipe ki a ma fẹnu kan ọrọ wọn NITORIPE IṢẸ AWỌN OLUKỌ KANPA.

Lati ọjọ ri · ti bẹrẹsi kọ ẹ·ọ oniwede yi a ko ti gbọ wipe awọn olukọni da iṣẹ silẹ kakiri gbogbo ilu ni Nigeria bi ti eyiti o ri ninu ọdun yi. A ko le ba awọn olukọni ti nwọn da iṣẹ silẹ na wi nitoripe ẹniti o wọ bata ni om, ibiti bata gbe nta on lẹsẹ.

A ni irọju ju ara wa lọ ṣugbọn bi ki a ṣiṣẹ nibikan bi ọdun mẹwa ki o mọ si ilọsiwaju nibẹ kọ ọrọ na ko ba oju mu rara. Awọn Yoruba ni bi a ko ba mọ ibiti a nlọ, dandan ni ki a mọ ibiti a gbe ti mbọ Nigbati awọn olukọ yi sun kan ogiri ni o mu wọn hu iru iwa ti nwọn hu yi.

Tani a ri ba wi ju awọn alamọjuto eto iṣẹ ijọba ilu wa ti nwọn NJẸKI NKAN NA PỌ SI IBIKAN *Nwọn ti gbagbe wipe gbogbo wa ni a nṣowo ogun, bi ẹja ba sọ lodo, a mọ i,e ti o to.*

Bi ko ba jẹ aifilafẹ ti ijọba wa fi igbe ti awọn olukọ wọnyi ti n e falẹ ni ọrọ ko ba ti buru to eyi.

Ju gbogbo rẹ lọ, a bẹ awọn olukọ awọ i ọmọ wa na ki nwọn owo i nwọn gbọ ileri ti Ọlọ'a Alhaji Tafawa Balewa, O'otu eto Ijọba ilẹ wa ṣe fun wọn wipe on a fi ọrọ edun wọn sero pẹlu awọn alabaro on, ki nwọn pada senu iṣẹ wọn.

Nitotọ ọmọ ale ni ri inu t. ki i bi.

---

## Odaran Fowo "Ogogoro" Sanwo Ori

ABA – Ọdaran ọmọ ilu Kilaa, A pan Udo Udo t a vọ i ọlọpa mi wi si iwaju adajọ kotu wipe awọn ikoko ooru ọti "ogogoro" meji mọ lọwọ ni ki adọjọ ṣe on pẹlẹ, owo ọti-ogogoro na ni on fi nsan owo-ori fun Ijọba.

Ọ·unrin ọdaran na bẹ apajọ kotu yi pupọ, o ni ọmọ mejila ni iyawo on bi fun on. o ni o ṣẹṣẹ tun bi iṣẹtala ti o ntọ lọọọ, nitorina bi adajọ bi sọ on sẹwọn awọn ọmọ y a di oniranu ebi a si mi pa wọn.

Awọn ọlọpa ti nwọn mu ọdaran na ni ni ọna ọja IkotSpẹnni ni agọn ri i ti o ru ikoko ooru ọti na lọ sọdọ awọn onibara re lati ta a.

Adajọ ni on fi eleyi fa a leti, ki o ma ṣe bẹ mọ ṣugbọn ki o o fi pọnun meji abọ tanran si kotu.

# Oyinbo Oni Tii Dosise Won Duro

APAPA — Ogunlọgọ awọn oṣ ṣẹ ile iṣẹ awọ i Oyinbo to nṣe ewe tii ni Apapa ati Port Harcourt bi i g b a ena ni awọn al ṣẹ ile na ti daduro lẹnu iṣẹ, ṣugbọn awọn alaṣẹ ibiṣẹ na ni lati bi ọjọ mẹjọ sẹhin ti nwọn ti da iṣẹsilẹ ni gbogbo wọn ti bẹrẹsi huwa ti ko dara'

Ohun to mu d da iṣẹ silẹ ni s san t nwọn ko san ẹkunowo lori owo oṣu a i e'e lori owo oṣu wọn fun wọn eyiti awọn ti pinnu si wipe iṣ ro rẹ y o bẹrẹ lati ọjọ kini oṣu kini ọdun yi gẹgẹbi iwadi ti Morgan ṣe ati ipinu ti Okot e - Eboh gbe dide gẹgẹb aṣoju fun ijọba apapọṣe nibi ipade ijiroro kan ti nwọn ti ṣe lori ọrọ ẹkunwo awọn oṣ ṣẹ ni Eko.

Ni gbangba ode ile iṣẹ na ẹniti o jẹ ọga agba, afunisọ Ọgbẹni B. Zallinger ti lẹ oriṣ riṣi iwe asọtẹlẹ lori idaduro a ọ i oṣiṣẹ abẹ rẹ bẹni a s tun gbọ pe inu ọsẹ to kọja, enia mẹta ninu awọn oṣiṣẹ na ni awọ ọlọpa t mu ninu iji kan to bẹ silẹ ni ita ile iṣẹ na lati igbati didaṣẹ silẹ ti bẹrẹ.

Ọgbẹni B A. Williams to jẹ alagbaṣọ fun awọn oṣ ṣẹ na bu ẹtẹ lu iwa ti awọn alaṣẹ ile iṣẹ na hu lori ọrọ yi, papa julọ nigbati o danun pe ' Ọpọlọpọ ile iṣẹ awọn Oyinbo onisowo ni nwọn ti san ẹkunwo titun yi fun awọn oṣ ṣẹ wọn.

Ṣ waju si o ni iru iwa buburu ti awọn afunisọ ile iṣẹ yi hu ni o ma mu ki ijọba ṣe ofin kan ti yio mu wọn san owo na tipatipa. Awon nkan to tun jẹ alaye pataki tori ẹkunwo ti nwọn ja fun ni nipa owo oṣoṣu ti ijọba nyọ pamọ lara awọn oṣiṣẹ fifi ọmọ ilẹ Nigeria ṣe alakoso ile iṣẹ t fi oju inu wo owo oṣu fun ṣ ṣẹ ẹkun rẹ ati sisan owo ile gbigbe fun wọn.



# Tisa Ni Awon Ni Awon La Awon Minisita Loju

EKO — Ere ni awada ni oro awon tisa ti nwon da ise sile kakiri gbogbo ilu se ngbojo sori a ko si ti gbo eyiti awon alakoso eto Ijoba wa fe se lori o r o awon olukoni na sugbon awon tisa ni se bebe l'Eko lojo ti Ijoba nse ajoyo ojo ti nwon gba Ominira agbatan ni ojo Alamisi ijewa

Onirohin wa ti o lo wora lodan ni gbogbo awon tisa ni nwon ko lati ko awon omo ilewe to lo si ibi eye ojo na, kaka ki nwon se bee nse ni nwon k pali akolewe lowo.

Okan ninu awon pali akolewe won na ti o pani lerin ni okan ti nwon ko oro si bayi 'AWA TISA NI [illegible] YIN LOJU NI ABULE ENYIN MINISITA.

Enikan ninu won tisa l'Eko na gbe apoti kan ru o ni lati bi odun meta-d n logbon ti o n[illegible] nko won nwon ko ti san ju ponun meto o di sile marun lo fun on nibiti on gbe ti nse tisa.

Awon onise irohin kan b i lere wipe nibo ni ilewe ti o ti nse ise o ni iyen ko kan won rara o ni oruko on ti o nje Opeo u Asa n nikan ni on le da fun won

Awon tisa ti Ibadan ati awon omo ilewe won ko tile lo si ibi aseye kan rara awon alakoso Ijoba orun ko tile se aseye iwode kan rara.

Ninu oso yi ni oro idasesile awon tisa na tun buroke debi wipe gbogbo awon obinrin ti nwon nta oja ti nwon lomo ile iwe ni nwon kawo leri lo sodo Olola Tafawa Balewa, olotu Ijoba nnu le ti o ngbe ni On kan l'Eko wipe ki o gba awon ki o tete soro kan pato nkan ti Ijoba ba fe se fun awon oluko ti nwon da ise sile ra.

Wo oju ewe kefa fun ti awon Soja ti owo nwon poora iwe.

# Ariwa Ko Ni Gba-wosi Ibo Didi

KADUNA — Gbogbo awon egbe os la ti nwon wa ni ipinle iha Ariwa ni a gbo wipe nwon ti se [illegible] lo lori lilo ede iwosi ni akoko ipolowo egbe fun ibo didi to mbo si ile igbimo aso lin ijoba apapose.

Nwon se ikilo yi ni akoko ipade ile igbimo ti ile Ariwa ni Kaduna ni ojo Alameta to koja, nigbati nwon ma se ikilo yi Olotu ipinle Ariwa Olola Alhaji Ahmadu Bello ati asiwaju egbe Olomi ni omo egbekegbe to ba huwa lilo eke eebu pelu ero lati da ijangbon sile lati le fi ri oju rere gbe r e. gba yio jiya lowo ile ejo to wa ni ilu Olola Ahmadu Bello tun se ikilo lori iwa ipata ti o le da rukerudo sile, ati pe enikeni to ba gbero lati hu iwa janduku yio ri ere re gba ni kotu.


E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin ELETI—OFE ti o kun fun irohin aladun losose.



BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE

KEROSINE

L'ayo!




Ti o ba ṣepe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ri ni nibikibi, ko si wọn, o mọ́ daradara, owun lo si dara ju fun onjo-sise, iná-titàn ati lati mũ ñ yàná Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

# Owo Osu Awon Soja Poora Oga Soja Ko Agbako

EKO — Ọgba awọn ṣọja ti nwọn npe ni Dodan Barracks ni Ikoyi di ọgbr onisiniKa ati wahala ni Ọjọ Ẹti to kọja nigbati awọn ṣọja nku lọ ku bọ, ti nwọn nsọpe afi bi nwọn ba san owo oṣu fun wọn kia ia, ọpọ ninu wọn si kọ lati kuro nibiti nwọn gbe to si.

Nigbati Alhaji Tanko Galadima, ti nṣe Minista eto iṣẹ awọn ṣọja ọkọ oju omi de ọgba awọn ṣọja wọnyi, o ba ọpọlọpọ ninu wọn ni iduro, ṣugbọn ni Ọjọ Ẹti yi, lẹhin wakati mejila o din diẹ ti nkan yi ti ṣẹlẹ, a gbọ pe ọga agba ṣọja kan ti orukọ rẹ njẹ E.C. Okafo to nṣe asanwo fun awọn ṣọja wọ inu ipebi itimọle lati ọwọ awọn ọlọpa.

Gẹgẹbi irohin ti o jade lati ile iṣẹ awọn ṣọja na, nwọn ni ẹgba lelẹdẹgbẹta ponun, ati ṣile mẹdogun (£2,500:15/:) ti nwọn fẹ fi san owo oṣu ti poora, ṣugbọn ni Ọjọ Ru to kọja, ni ọga agba ṣọja lọ gba ẹgbaji le ọ-o lerugba ponun o le meji, ṣile mẹdogun ati kọbọ mẹjọ (£4,22.15/-8d) lati Banki nla to wa l'Eko, fun owo oṣu awọn ṣọja.

Ni Ọjọ Bọ to kọja, ọga ṣọja na ja wọ iku ọgba bi were pẹlu oYije loju, o ni nwọn ti gbe ponun marud din lọgọta lọ (£55) ninu owo, aṣe nikẹhin ni nwọn wa mọ pe ki iṣe iyẹn nikan bikoṣe ẹgba le ledẹgbẹta ponun ati ṣile mẹdogun ni o sọnu.

Ni Ọjọ Ẹti, awọn ọlọpa fi yeni pe awọn ti mu ọga ṣọja na fun ibere ọrọ lori nkan yi, nigbati nwọn bi ọkan ninu awọn ọga ṣọja kan bere boya o ni ọkankan lati sọ si ọrọ yi, o ni "Ko si alaye kan an na," ṣugbọn lona ọna nwọn sanwo fun awọn ṣọja na.

## Nwon Da Adajo Kan Duro Ni Ibadan

(O bẹrẹ loju ewe kọ(a)

ati akọsilẹ adajọ yi.

Igbimọ ijọba ibilẹ Iwọ Orun ni awọn ti gbe igbimọ miran dide lati foju inu wo aroye ti Oloye Agbaje ṣe si iu iwe to kọja yi nwọn si sọ pe lori eyi, awọn ti paṣẹ pe ki adajọ na dawọ iṣẹ na duro na titi esi i ad igbimọ ti nwọn gbe dide yio fi jalẹ.

Nibere ọsẹ to kọja Oloye Agbaje sọfun igbimọ ijọba ibilẹ Iwọ Orun wipe ẹ wọn ni nwọn gegebi adajọ kotu ibilẹ ni Ibadan.




PROGRESSIVE BUSINESS GOES FORWARD BY RAIL

If you want to expand your market or industry, you can benefit from the *dependable and low-cost* services and facilities offered by the Nigerian Railway Corporation.

Freight trains on Nigerian Railway Corporation's 1,700-mile system (plus many miles of siding) travel north and south, east and west, all the year round, day and night, providing the vital link of the vast Nigerian Federation. Industries are linked to their markets, produce centres to the ports, little villages to big towns, all along the line.

You can count on the thorough co-operation of the Nigerian Railway Corporation at the ports, produce and industrial centres and at any of its 200 and more stations.

And what's more : you are dealing with people you can trust.

SEND YOUR GOODS NATION-WIDE BY RAIL





## Radio Book Review:

# How To Listen To The World News

By Oialekan Onatade

Radio and television sets are becoming increasingly well known in Nigeria. Nigerian housewives and students have taken great interest in local television programmes, and it is a very common scene to see the average worker carrying his transistor radio set to his working place every day.

BUT there is one missing link-that is dearth of radio books in local bookstalls, whereas people want books showing them how to tune their sets properly and how they can know all radio stations of the world and so on and so forth.

European publishers for the pass few years have been busy compiling books on modern radio and television sets, one of these is an annual WORLD RADIO TELEVISION HANDBOOK published by WORLD PUBLICATIONS of Hellerup, Denmark (22/-).

A world-wide publication, the book is radio encyclopedia in itself though it is not at present available from the local bookstores the 18th (1964 edition) which I just received by post contains particulars about all broadcasting and television stations over the whole earth.

For instance, I opened the pages devoted to African radio stations and I saw one page marked Nigeria (Republic of). The information given about our local NBC is up-to-date.

Starting from Lagos (the capital) up to Ibadan, Enugu and Kano, I can tell you through the book what is the power of transmitters they are using in any of these stations and what time I can listen to their local news item.

Not these alone, WORLD RADIO TV HANDBOOK gives world times in all countries from Greenwich Mean Time (GMT) to American Standard time up to the time in Middle East.

Although I am a novice in wireless theories but through many years of practical experince I gathered that locating certain shorwave broadcasts are very difficult at times. If you study this book under review it will help you to understand some of the situations you may enbounfer from time to time when turning your radio set for eetter reception.

In fact "WORLD RADIO TELEVISION HANDBOOK guides you around the world with your radio another book of its kind (published by the same publishers) that I can recommed is THE NEW GUIDE: HOW TO LISTEN TO THE WORLD. They are books you have to look for and the whole radio world is right at your finger-tiss if you have these books in your book shelve.



'EMERY AT LARGE'

### 'Emery At Large'

Of 'EMERY AT LARGE", the Star Dick Emery explains : "It's me playing different charcters in various situstions. You could it EMERYWHERE;.

Dick Emery's first radio series and is currently being broadcast in the BBC General Overseas Service.

Read and Advertise In

Eleti-Ofe

Your Weekly News Paper

## Iyawo To Poko Re Lejo Padanu

EKO — Iyaafin Victoria Coker ni a gbọ pe o pe ọkọ re, Ọgbẹni Victor Lanipo Coker lọ si ero lati gba ile ti on ati ọkọ re ngbe gẹgẹbi onile, ile naa si wa ni opopo Willoughby ni Ebute Metta, sugbọn o padanu ejọ na nigbati adajọ ni ki o lọ san ponun marun din lọdọta (£150) fun owo iranwọ o si fu ejọ na ka.

Ninu ejọ ti Iyaafin Coker pe o sọ fun re wipe ile ti ọkọ on kọle je lori, on ni o ni, ati pe owo baba on ni on ti gba awọn nkan ti awọn fi kọle.

Nigbati adajọ Ọgbẹni Lambo ma ṣedajọ na o ni on gba alaye ti lọya ọkọ se wipe biotilẹ je pe iyawo lo ni ilẹ ti ọkọ re kọle si, sibẹsibẹ apa kan ẹgbẹdogun pọun (3000) orire ti ọkọ re je ni o fi kọ ile na, eyiti o fi orukọ iyawo re ta, ati pẹlu awọn orisirisi owo ti ọkọ tun na lori ile na.

## Akintola Di Are Onakakanfo L'Ọyo

ỌYỌ — Irẹhin ko to afojuba nị ẹyẹ oye Arẹ Ọnakakanfo tị nwọn ṣe fun Oloye Samuel Ladoke Akintọla Olotu Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ti Ọba Alafin Bello Gbadegẹsịn Ladịgbolu Keji fi je oye Arẹ Ọnakakanfo nị Afin rẹ ni ọja Akẹsan ni ịrọlẹ ana ọjọ Eti.



**Oloye S. L. Akintola**

Gbogbo ẹse awọn gbajumọ enia atị awọn ijoye pẹlu awọn ọba ni nwọn pe ṣọṣọ sibẹ ni oju gbogbo wọn ni Oloye Busari Ayinde Osiefa Ọyọ fi fi Oloye Akintọla le ọba Alafin lọwọ gẹgẹbi aṣa idile wipe kị o di a lo'a Oye Arẹ Onakakanfo na.

Lẹhin eyi nị nwọn pe Oloye P. A. Afọlabi Jagun Ọyọ wipe kị o sọ ita ṣoki nipa Oye Arẹ Onakakanfo na A gbọ wipe ninu awọn meji'a tị nwọn ti jẹ Oye na ni ile Yoruba ni KUNRUMI tị ORILE IJAIYE, LATOSA ti ilu IBADAN atị OJO ABURUMAKU ti Ogbomọsho, Oloye Akintọla ni o dị ẹkẹta la.

Lehinti nwọn tị gbe ọpa Ojurọ ti oye na fun Oloye Akintọla tan ni Ọba Alafin wa fi nkan mimu ati nkan jịjẹ te gbogbo awọn ti nwọn wa sị ịbi oye na lọrun ninu agbala faaji rẹ ti ilu aro ati ṣẹkẹre si nke kankan.


## Electricity Corporation Of Nigeria

### Vacancy For Cost Accountant

Applications are invited from suitably qualified Cost Accountants for appointment as Senior Accountant in the Accounts Department of the Electricity Corporation of Nigeria.

QUALIFICATIONS:

Candidates must possess the A.C.W.A. qualification and should have had at least 5 years post qualification experience with an industrial concern.

DUTIES OF THE POST:

The Cost Accountant will be responsible to the Chief Accountant for all standard costing with a view to determining and analysing costs.

AGE:

Candidates should be between the ages of 30 and 40 years.

SALARY SCALE:

The Salary of the post will be scale 12 (Middle Segment) — £1,303 x 63 — £1,681 p.a.

CONDITIONS OF SERVICE:

The post is pensionable and appointment will be on probation for three years.

METHOD OF APPLICATIONS:

Application Forms which must be completed in duplicate are obtainable from the Chief Personnel Officer, Electricity Corporation of Nigeria, Headquarters, 24/25 Marina, Lagos and they must be returned to him not later than the 9th of November, 1964.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370; Editor, (Oloru) Ola Onatade 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O 467, Lagos,